# Ìlépa Ìdàgbàsóké Tó Dúró Ṣinṣin (SDGs)

*“Ayé yìí  kan náà laní. Kọ̀ sì sí ibọ̀míràn tí a lè lọ. Tí a bá lo ọgbón àtinúdá a wa dáradára, a ò nílò ibọ̀míràn. Tí a bá mójú to o, àti olúkúlùkù ara wa, gbogbo ohun tí a bá fẹ́ ḿbẹ ní ayé yìí”*

**Alàgbà Ken Robinson**
**Òǹkọ̀wé/Olùdánilẹ̀kọ̀ọ́**

## Ìṣàfihàn Àwọn SDGs

### Iṣẹ́
Èyí lè wà fún lílò ní àpèjọ akẹ́kọ̀ọ́, àsìkò olùkọ́ tàbí iṣẹ́ ṣíṣe nínú ẹ̀kọ́ kíkọ́.

### Àbájáde Ẹ̀kọ́
Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè sàlàyé ohun tí Àwọn SDGs fún àgbáyé jẹ́ àti ìṣe pàtàkì wọn ọn.

### Ìgbáradì
Bí ó bá ṣeéṣe, tẹ̀ kí o sì ṣe àfihàn Àwọn SDGs ní iwájú iyàrá ìkàwé tàbí ní orí ẹ̀rọ aṣàfihàn nípa lílo atọ́kasí kejì tàbí kẹta (appendix 2 or 3). Pèse pátákó ìkòwé láti kọ àbá àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Tẹ̀ tàbí kí o yà ìwé kékèké fún ìdárayá òpin iṣẹ́.

### Láti ṣe ìwadìí síwájú si
Fún àlàyé kíkún nípa Àwọn SDGs, kàn sí orí ẹ̀rọ ayélujára www.globalgoals.org

Fún
- Ìmọ̀ràn lórí àti kọ́ nípa Àwọn SDGs
- Ìwé pélébé lórí Àwọn SDGs fún àwọn ọmọdé
- tẹ̀síwájú tó jinlẹ̀ lórí ìgbáradì fún ẹ̀kọ́ nínú Àwọn SDGs àti ìtọ́kasí àfikún àwọn ohun èlò.
- Ibi Ìṣàfihàn àwọn fọ́tò SDGs
- Ìrànlọ́wọ́ ní gbígba àwọn ọmọdé níyànjú láti gbé ìgbésẹ̀

Kàn sí: worldslargestlesson.globalgoals.org/resources-for-teaching-the-sdgs-in-nigeria/

Gbogbo Asiko

ọgbon iṣẹju

Ọjọ ori

Mẹjọ si Mọkanla

# Ìṣàfihàn Àwọn SDGs

## Àgbékalẹ

iṣẹju mẹwa

Gbàrà tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ bá ti wọ yàrá ìkẹ́kọ̀ọ́, ṣe àfihàn ìbéèrè yii – **‘Kíni àwọn ìṣòro tí ó ga jùlọ tí ó ń kojú àwọn ènìyàn ní àwùjọ/orílẹ̀ èdè/gbogbo àgbáyé?”** (Lo eyikeyi)

Gba àwọn akẹ́kọ̀ọ́ níyànjú láti ronú pẹ̀lú ìwòye ẹlómíràn. Bí àpẹẹrẹ, o lẹ̀ sọ wípé **“A fé kí ẹ ronú bí olórí orílẹ̀ èdè!”**

Kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ joko ni méjìméjì. Jẹ́kí wọ́n gbìyànjú láti mẹ́nuba àwọn iṣoro t’ótóbi jùlọ tí ó ń kojú agbègbè wọn, orílẹ̀ èdè wọn tàbí àgbáyé. Gba àbá láti ìsòrí kànkan. Àwọn wọ̀nyí ni a lè kọ sí orí pátákó ìkòwé.

Lo atọ́kasí kinni (appendix 1) fun ìrànwọ́ bí ó bá pọn dandan.

## Àwọn SDGS

iṣẹju marun

Fi àwọn SDGs han àwọn akẹ́kọ̀ọ́ nípa ṣíṣe ìtọ́kasí àwọ Ìlépa tàbí àfojúsùn tí ó jẹ mọ́ àwọn ìṣòro tí wọ́n ti mẹ́nu bà. Ṣe àfiwé àwọn àkójọ ìṣòro tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kọ pẹ̀lú àwọn Ìlépa Ìdàgbàsókè Tó Dúró Ṣinṣin tí a ṣe àfihàn rẹ̀ níwájú.

Fún àpéjọ àwọn akẹ́kọ̀ọ́, o lè mú kí akẹ́kọ̀ọ́ mẹ́tàdínlógún dúró síwájú kí wọ́n kọ ẹ̀yìn sí àwọ n ẹlẹgbẹ́ wọn. Ọ̀kànkan àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò di ìwé ìlẹ́wọ́ kan dání tí a kọ ọ̀kan nínú àwọn SDGs si. Bí ẹnikẹ́ni bá daba ìṣòro kan, akẹ́kọ̀ọ́ níwájú tí ó bá mú ìlépa tí ó jẹmọ dání, yóò yíjú padà.

## Ní Òye SDGS

iṣẹju mẹwa

Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wo ìwò-àrà Alàgbà Ken Robinson lórí ìfàwòránhán ńlá, ẹ̀rọ kọ̀mpútà tàbí kí wọ́n parapọ̀ lórí jorí láti wò ó lórí ẹ̀rọ alágbèéká worldslargestlesson.globalgoals.org/resources-for-teaching-the-sdgs-in-nigeria. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tún lè ka ìwé ìdárayá láti orí www.globalgoals.org/worldslargestlesson nípa yíyí awẹ́ ojú ẹ̀rọ alágbèéká tàbí ọpọ́n ìmọ̀ (mobile phone or tablet).

## Iṣẹ́ Ṣíṣẹ

iṣẹju mẹwa

1. Láti parí ẹ̀kọ́ nà, jẹ́kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kọ gbólóhùn kan t’ófi òye wọn hàn lórí SDGs àti àwọn nǹkan tí ó bá jẹ́ sí wọn. Fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní òdiwọn ọ̀rọ̀ tí ó yẹ kí wón lò láti fi ọ̀rọ̀ ránṣẹ́ lórí Twitter sí **@WorldsLessonNG #WorldsLessonNG**
2. Tẹ̀ tàbí ya àwọn ilà onígunmẹ́rin ọgbọọgba (squares) oní ìwọn sẹ̀ntímítà méjìlá sí sẹ̀ntímítà méjìlá (12cm x12cm) sí orí tákàdá. Fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní tákàdá onígunmẹ́rin ọgbọọgba yii tí a kò kọ ohunkóhun sí kí wọ́n sì ya àwòrán apanilẹ́rìn-ín ara wọn gẹ́gẹ́ bíi alágbara. Sọ fún wọn kí wọ́n fi ọ̀rọ̀ kún ẹnu àwòrán nà irúu ọ̀nà tí wọ́n lè gbà fi ran SDGs lọ́wọ́. Gba àwọn ìwé nà kí o ṣe àfihàn an rẹ̀ nílé ìwé, ṣe alabapin rẹ pẹ̀lú wa lórí Facebook ní **@WorldsLessonNG**

# Àwọn Ìṣòro tì àwọn ènìyàn ń dojúkọ lóde òní (lò ó bí ó bá ṣeéṣe)

- Òṣì
- Àìdọ́gba àwọn orílẹ̀ èdè
- Ebi
- Àìlera àti àrùn
- Omi ìdọ̀tí
- Àìnììmọ́tótó
- Ẹ̀kọ́ àìpéye — ọ̀pọ̀ ọmọ ni kòlè lọ ilé-ìwé
- Iṣẹ́ tí kò lérè àti àìtó iṣẹ́
- Ìfàséyìn ọrọ̀ ajé — àìtó owó fún orílẹ̀ èdè láti ṣe ojúṣe fún àwọn ará ìlú
- Àìdọ́gba laarin akọ àti abọ— àwọn okùnrin àti obìnrin ò ní àǹfàní kan naa
- Ogun, ìjà àti làásìgbò
- Ìbẹ̀rù boju
- Rúkèrúdò laarin àwọn ènìyàn
- Ìwà ìbàjẹ́ àti àìsí ìdájọ́ òdodo
- Àìní-ìbọ̀wọ̀ fún ẹ̀tọ́ ọmọ ènìyàn
- Àìní-ìfọwọ́sowọ́pọ̀ laarin àwọn orílẹ̀ èdè
- Àísí-iná láti gbé ìgbé ayé t'órọrùn
- Àwọn ohun amáyédẹrùn àti ọ̀nà ẹ̀rọ ìbára-ẹnisọ̀rọ̀ yẹpẹrẹ
- Àìsí àbò tó péye ní àwọn ìlú
- Àìdúró ṣinṣin àwọn ìlú nípa lílo àwọn ohun tó ju agbára wọn lọ
- Ìfiṣòfò àwọn àlùmọ́nì àti àìsí àtúnlò
- Ìyípadà ojú ọjó
- Kíkó àbàwọ́n bá àwọn òkun àti agbami
- Àwọn ibùgbé tó ti dìbàjẹ́
- Àìní àǹfàní si ẹ̀rọ ìgbàlódé, kọ̀mpútà àti ẹ̀rọ alágbèéká
- Àwọn ènìyàn ò ní ìgbẹ́kẹ̀lẹ́ nínú ètò àbò tó dájú
- Sísanrajù
- Ẹlẹ́yà mẹ̀yà
- Dàrúdàpọ̀ nínú ìletò káàkiri

# Ìlépa Ìdàgbàsókè Tó Dúró Ṣinṣin



# Ìlépa Ìdàgbàsókè Tó Dúró Ṣinṣin

